# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 584 MONDAY APRIL, 20 1964 (2D)


## Ọkunrin Kan Ṣepe Fun Awolọwọ, Tan O Fi Oju Gun IGi !

OBALENDE:— Ni Ọjọ Aiku ti iṣe Ogunjọ Oṣu yi ni awọn Ọdọmọkunrin kan parọ/ọ si ibudo bọọsi Ọbalende ti Oṣupa siya tọ o loke ti nwọn bẹrẹ sọrọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Ijọba mba ṣẹjọ l'Eko disisiyi.

Nibiti gbogbo wọn ti nsọrọ pe, "Ki Ọlọrun jẹki o pada wale layọ ati alafia ni ọkan ninu awọn enia ti o duro nibẹ ti o nje Sakiọsi ba dahun ti o si sọ pe, "Nitootọ Ijẹbu ni on, awa Ijẹbu si ni ọgbọn ninu, ṣugbọn ki iṣe ọgbọn ole iru eyi ti Awolọwọ gbọn, Ọlọrun ma jẹki o pada wale"

Gbogbo awọn enia ni nwọn nṣe, Ha ! *Ha* ! ! *Ha* !! !, iwọ ẹlẹnu burukuburuku Ijẹbu yi, ẹnu rẹ gba a lati sọ iru ọrọ abuku bayi si Awolọwọ, nigbati ọrọ na fẹ di ija ni Sakiọsi ba binu kuro lọdọ wọn, bi nwọn ti mbu, ni on na mbu wọn lọ ti o si nṣepe fun Oloye Awolọwọ.

Ṣugbọn Ọgbẹni Sakiọsi ko ti rin ese bata mẹdogun lọ, bi o si ti nfi ẹhin rin lọ ti o mbu Awolọwọ, oju ti o ni ki on yipada ki o ma a lọ ni o ba fi oju gun ọpa ti ọkunrin kan nru bọ lọna.

Lẹsẹkẹsẹ ni sakiọsi wolulẹ, ti ariwo ta gee, awọn enia na ni, "Ọdalẹ, Ori Awolọwọ mu ọ "awọn enia ko susi rara, ni Ọkunrin ti o ru Ọpa na ba ṣokalẹ, nigbati awọn yoku fi uṣẹ yọọ.

Oniwe irohin wa Ejongbọro ti Oran na sọju rọ ṣe alaye fun wa pe, Obinrin kan ni o ṣe itọju Sakiọsi, o si fi mentọletọ pa Oju Ọgbẹ na fun Sakiọsi itiju ko jẹki o le pada si Ọdọ awọn ẹlẹgbẹ rẹ mọ.

## Adajọ Agba Sọ Pe:

# PELEPELE DI OWO ENYIN ONIWE IROHIN NINU ỌRỌ YI !

EKO:- Gbogbo Ile ẹjọ lo palọlọ nigbati Ọlọla Adetokunbọh Ademọla, Olori gbogbo awọn adajọ Agba fun Apapọ Ijọba Naijiria nkilọ fun awọn aṣoju iwe Irohin ninu Ile ẹjọ gigajulọ pe, ki nwọn ṣe pẹlẹpẹlẹ ninu Irohin ti nwọn nkọ sinu iwe Irohin wọn ki nwọn si ma a ri dajupe, ohun ti nṣẹlẹ ninu Ile ẹjọ na gan an ni nwọn ntẹ si ita fun awọn araiye lati ma a ka, ki nwọn o ma ṣe bu kun Irohin na bẹni ki nwọn o maṣe dinku ninu rẹ.



Ọlọla Ade. Ademọla

Ọrọ yi ni Ọlọla Adetokunbọ Ademọla sọ nigbati ọgbẹni Olu. Ayọọla pe akiyesi adajọ Agba na si ori ọrọ ti iwe irohin kan (ki iṣẹ iwe Irohin Imọlẹ) gbe jade ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun osu yi eyiti akọle rẹ sọ pe" Idarudapọ be silẹ ninu kotu eyiti adajọ na pe ni "isọkusọ" atipe o jẹ irohin ti ko kun to.

Lẹhin eyi ni adajọ wa se ikilọ ti o si sọ pe, "pẹlẹpẹlẹ di ọwọ nyin oniwe irohin, ohun ti o ba ṣẹlẹ gan an, ni ki ẹ ma a ṣe amọrewo Alugbedu, ti o fi ọwọ ọtun ju titi ti o ni awọn enia ko ti ri tan wo, o di igbati on ba fi ọwọ osi lu u ni ẹo to ri nkan.

Lẹhin na ni ọgbẹni Olu. Ayọọla ọkan ninu awọn agbẹjọro ti o ngbẹnuse fun Oloye Awolọwọ wa mba ọrọ rẹ lọ lori ọgbẹni Latifu Jakande, Alakoso Ile iṣẹ "Allied Newspapers" pe, ki si ohun ti o kan an ninu ẹjọ ti o delẹ yi

Ọgbẹni Olu. Ayọọla sọ pe, adajọ si ara rẹ lona lati ṣe idajọ pe ki Ọgbẹni Jakande o lọ si ẹwọn ọdun mẹẹẹ lori ẹsun ti ko mọ ọwọ ti ko si mọ ẹsẹ.

O wa rọ Igbimọ Ijoko awọn adajọ pe ki nwọn maṣe kọ ibi ara si idajọ adajọ kotu giga, ki nwọn si fi Ọgbẹni Jakande silẹ.

O tun wa ṣe alaye ọna pataki marun ti adajọ gba ṣi ara rẹ lọna, ti o si rọ ile ẹjọ lati gbe igi le idajọ akọkọ ti adajọ ṣe.

Gẹgẹbi alaye rẹ, Ọgbeni Ayọọla sọ wipe lori ẹsun marun yi ni adajọ se idajọ le lori.

(1) Ọgbẹni Jakande fi ọrọ wa awọn enia kan lẹnu wo ni Ibadan ninu ọdun 1961, lati ko nkan ogun wọlu.

(2) Atipe owo ti o san fun awọn kan eyiti Ọgbeni Henri Oleari ati Anthony Oboh sọ niwaju Ile ẹjọ ati owo ile ero ti awọn enia na sun, Jakande lo san.

(3) Bẹni Ọgbẹni Jakande wa ninu ipade kan ti Ọgbẹni S. G. Ikoku ṣe, nibiti o ti da awọn enia kan sọrọ pe, awọn yio ko awọn enia kan lọ si Ghana lati lọ kọ iṣẹ ogun ki awọn le ba fi ipa gba Apapọ Ijọba orilẹ ede yi.



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

(4) Ọgbẹni Jakande lo ṣe eto lati ran awọn enia kan lọ si Ghana lati lọ kọ iṣẹ Ogun.

(5) Ọgbẹni Jakande lo gbero tabi ṣe eto lati ko awọn nkan ija ogun wọlu lati fi ipa gba Apapọ Ijọba Naijiria ki nwọn si gbe ogun ti ọbabinrin Gẹẹsi.

Ọgbẹni Olu Ayọọla ṣe alaye fun Ijoko Igbimọ awọn adajọ na pe, adajọ si ara rẹ rẹ lọna ninu eto eto ofin idajọ nigbati o ṣe apejuwe Jakande gẹgẹbi "Olori gbogbo nkan ti o delẹ yi" nitori idi eyi, o ni ẹsun ti awọn Ọlọpa mbaa ṣe ẹjọ le lori.

O wa bi awọn adajọ lere pe, "Ọna alupaida wo ni adajọ gba ti o fi le mu da gbogbo enia loju nigbati ko si ẹjọ lati ọdọ awọn ẹleri pe, o ba wọn ṣe ipade bẹni'l ko si lọ si Ghana."

O tun ṣe alaye pe Adajọ si ara rẹ lọna nigbati o gba eri awọn ọgbẹni Oliari ati Oboh gbọ, nitoripe eri awọn enia mejeji na lodi si ara wọn, eri wọn ko si dogba.

Siwaju eyi nigbati Ile ẹjọ na dide lati sin mi fun igba diẹ, fun iṣẹju mẹdogun, ni awọn enia ti o wa nile ẹjọ ni wa ngba ọgbẹni Ayọọla lọwọ ti nwọn si nyọmbọ rẹ.

Bi awọn enia ti ngba ọwọ lọwọ Ayọọla ni nwọn ngba ọwọlọwọ Ọgbẹni Ayọ Akinsanya ti nwọn si nsọ fun un pe, "Mo ba ọ yọ onti jare ninu ẹjọ yi na, Ayọọla ti fa aṣọ ya loju e'gun, oti sọ oju abẹ niko, koko ọrọ ti o wa nidi ọrọ na loti sọ yi, awọn adajọ ti rẹrin nigbati o mu ẹnu kan, ẹjọ rẹ ti jare".

Ariwo awọn enia yi pọ to bẹ gẹ ẹ ti awọn ọlọpa ti sare wọ inu ile ẹjọ wa pẹlu olugbongbo lọwọ ti nwọn le oju koko si awọn enia na pẹlu igbe pe, "E dakẹ nbẹ, ẹ ye pariwo mọ, ẹo mọ ibiti ẹ wa ni ?"

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia na dakẹ jẹ ẹ, ti nwọn si nwo ara wọn loju pẹlu iberu-ọkunrin kan ti o nmu kokakola ni asiko na sare gbe igo kokakola silẹ pẹlu iberu-bojo. Ṣugbọn ko pe pupọ

Wo oju Ewe Kẹfa

# ENYIN ỌMỌ YORUBA, Ẹ JẸKI A RONU

**Lati Ọwọ Latifu Babalọla**

MO ki gbogbo enyin Onkawe Irohin Imọlẹ ku ọjọ mẹta, ẹ si ku ipalẹmọ ọdun Ileya ti o ku diẹ niwaju wa yi, ki Alla jẹki ọdun na de ba gbogbo wa ni ayọ ati alafia ki ẹnikẹni maṣe ọdun na ninu aisan, ki o si pese owo tutu ti a o fi ṣe ọdun na fun olukulubu wa.



Hubert Ogunde ati awọn elere rẹ.

Loni, Ọmọ pe gbogbo ẹnyin ọmọ Yoruba ni ile, l'oko lati tẹ ti ko si ọrọ mi nitori akoko to fun gbogbo wa lati ronu jinlẹ ka si wo gbogbo ohun ti o nṣẹlẹ nisisiyi si awa ọmọ Karọ-o-jire ni Ipinlẹ Iwọ-Orun atini Naijiria ni Apapọ.-

Yoruba! Yoruba!! Yoruba-o-o Yoruba-o-o-o, nibo ni awa Yoruba wa loni, kini ṣẹlẹ si wa? Ha! ẹ jẹki a ronu daada, ki afọwọsowọpọ fun ire ilẹ wa, ẹ jẹki a ranti awọn iran ti o mbọ, nitori ohun ti a ba ṣe silẹ loni ni nwọn yio ba itan si ni yio tun jẹ lọla.

## YORUBA RONU!

Gẹgẹbi ere ti Ọgbẹni Ogunde ṣe laipẹ yi ti o sọ pe ki awa Yoruba ronu ododo ọrọ ni ere Ọgbẹni na! Ironu si to fun ẹniti o mọ oye, ki nṣe nitori pe ọrọ oṣelu ni Ọgbẹni Ogunde ṣe ere na ṣugbọ ki o le mu wa ronu, nitoripe awọn ti oye ko ye to le ma sọ pe nitori Oguude jẹ ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan ni o ṣe ṣe ere yi, ọrọ yi ko ribẹ rara, o yẹ ki awa na rori wa wo nipa aye ti awa Yoruba wa loni ati iru ohun ti o nṣẹlẹ si awọn ọdọ ti o ṣẹṣẹ jade iwe mẹfa tabi iwe mẹwa nipa airiṣẹ ṣe.

## ỌMỌ ILE—IWE

Ko si iṣẹ fun awọn ọmọ wa ti o ṣẹṣẹ jade iwe mẹwa, dipo ki awọn ọmọ wa ri iṣẹ ṣe, ọmọ ilẹ Ariwa oniwe mẹrin ni nwọn ngba si iṣẹ, ti nwọn si ngbe wọn si ipo Ọga Agba.

Gbogbo aye ile iṣẹ Ijọba ni nwọn ti fi ọmọ ilẹ Hausa si bi o tilẹ jẹpe nwọn ko mọ iṣẹ na ṣe ti imọ won ko si to ani ọmọ wa oniwe mẹwa ni nwon yio tun gba ni ọmọ ọdọ fun un lati le tun ma kọ ni iṣẹ ki ole tete mọ iṣẹ re.

Laipẹyi ni Oloye Fabgenro Beyioku binu jade ninu Ile-Igbimọ Agba oṣelu nitori ipo Alakoso Agba Oṣelu.

Ati paapa julọ iru ipo ti awa Yoruba wa ninu ile-iṣẹ nla Ijọba, ki a tilẹ tun wa fi ẹnu kan ti Ile-Aṣofin. Mo fi ara mọ bibinu jade Oloye na, ara. Ohun ti a ṣi ṣe nṣọ lọwọ ni yẹn.

## ILE—IGBIMỌ IJỌBA

Gẹgẹbi gbogbo wa ti mọ pe Oloye Osadebay ni Alakoso Awọn Agba-oṣelu tẹlẹ ti o si tun jẹ oye Alakoso Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ-Orun lẹhin ibo ti wọn di wọle laipẹyi ni orukọ Ẹgbẹ Alakukọ Nwọn si ni lati yan elomiran si ipo rẹ dipo ki nwọn tun mu ọmọ Yoruba ọmọ Ibo ni nwọn tun mu

Tabi kosi Yoruba ninu N.C.N.C. ni, tabi ko tun si ọmọ Yoruba ninu ile igbimọ na mọ ni? Akọkọ ti nwọn kọkọ jẹ oye na ọmọ Ibo, ekeji ọmọ Ipinlẹ Agbedemeji, otun wa di ẹlẹkẹta ọmọ Ibo ni nwọn tun lọ yan nbo ni Yoruba wa?

Bakanna ni ẹnu lọlọyi ni nwọn tun fi awọn ọmọ ile Ibo meji si ipo minista awọn ni Ọgbẹni K. O. Mbadiwe ati Ọgbẹni Amechi, nitorina njẹ ele ko ha to ki a ronu wa wo?.

## KINI TI WA TI JẸ

O yẹ ki a bere lọwọ ara wa pe ki ni ti wa ti jọ tabi kini o fa gbogbo eleyi, tabi a jọ ja fun ominira yi kọ? Tani ja fun ominira yi ju

Nitorina o ki a ba ara wa sọrọ, ki ayọ ifẹ owo kuro ni ọkan, nitori owo ni da gbogbo eleyi silẹ, ẹ jẹki a yọ ifẹ owo kuro ki a sowọpọ.

Awa ni o jẹ pe awa ni awọn ilẹ yoku nwo ṣe ohun gbogbo. Kini o wa de si wa loni? ẹ jẹki a ronu, Ọlọrun kori sọ wa-di ero ẹhin, ẹ maṣe jẹki ọgbọn wa tun pa wa ni ara, ẹ jọwọ ẹ jẹki a lo ọgbọn ti Ọlọrun fun wa lati fi tun ilẹ ṣe ẹnyin ọdo ọrọ na tun di ọwọ nyin ẹ jẹki a ba awọn obi wa sọrọ.

Nitorina asiko to fun awọn ọmọ Yoruba lati ronu jinlẹ nipa aye ti awa loni. Bi ẹnikẹni ba ni ọrọ yi ko ou irọ ni o npa, sugbọn ki o tun rauti ẹhin ọla.

Wo Oju Ewe Kẹfa

---

# Awọn Meji Jona Sinu Ile Itura

CHICAGO:- awọn enia meji ni wọn joku sinu ile itura ati awọn enia mejila ni o si fi ara gbọgbẹ pẹlu ni owurọ ọjọ kejila oṣu yi.

Awọn enia to wa nibẹ sọ pe wọn ko mọ ohun to fa ina na ṣugbọn wọn si fi ye onirohin wa pe awọn ti wọn joku sinu ina na si jẹ pe, ina na si si tete kan wọn ni ara Awọn to fi ara gbọgbẹ ko jẹ ohun to lewu pupọ.

Onirohin wa fi ye wa pe awọn to jẹ pe ina na kan ni ara pupọ ni o si fi ara gbọgbẹ pupọ ju nigbati won ngbinyanju lati fo feresee inu ile na

Awọn to fi ara gbọgbẹ na si wa ni ile iwosan ti Chicago

# Awọn Ole Gbe Mọto Agbaje Lọ

IBADAN:- Ni alẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni awọn ole kan gbe Mọto Ayọkẹlẹ Oloye A. M. F. Agbaje ti o ti jẹ alakoso eto irohin tẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tẹlẹ ri.

Oloye Agbaje gbe mọto Alajapa (Volkswagen) si oju ile rẹ ni Ogunpa atijọ ibẹ na ni mọto ayọkẹlẹ na ti di nkan ti wọn ko ri mọ

Awọn Ọlọpa to wa ni apakan ti nṣe idari nipa ọrọ mọto ti bẹrẹ si wa mọto ayọkẹlẹ bayi nọmba mọto ayọkẹlẹ na si jẹ WA 7650.

# Obinrin Afọju Kan Pada Riran

IGANDO:- Agbọ irohin wipe obinrin Adelebọ kan ẹniti oju rẹ mejeji ko riran fun iwọn ogun ọdun ni iwọn akoko ti ko fi riran wọnyi ọmọ mẹta li o bi.

Ni ọjọ kan, nigbati awọn Atinga nṣere ọdun ni ilu yi, obinrin afọju ti a npe ni Adenikẹ lọ si bẹ boya on yio ri iwosan

Bi o ti de ọhun, o ba wọn nibiti nwọn nṣe ere o si duro, ọkan ninu awọn to ṣe atọkun rẹ de ibiti awọn Atinga gbe nṣere so fun pe, ki o majo? Adenikẹ dahun pe, kini ohun ti o nya apari lori, ti o fi mọkunkun ninu odo. Mo ṣebi ẹniti inu rẹ dnn bi o njo, ti o si nyọ! sa ju mi silẹ o jare.

Gbogbo enia si kẹnu bo o pe, nigbati o mọ pe on ko ni jo ki o wa sikin fun ni Adenikẹ ba gba o si bẹrẹ si jo. Lo ju iwọn igba diẹ ti o bẹrẹ si jo, ni oju rẹ lati o si ọwọ gbogbo enia bi nwọn ti njo bẹni oa gbe si lẹlẹ o di le, ẹnu ya a lati ri pe a ṣe on tilẹ bi awọn ọmọ ti o dagba to yi.

Nibiti o gbe nwo ara rẹ ninu jingin biri ni oju rẹ tun dudu ti ko si riran mọ.

Lẹsẹkanna obinrin yi sare odi ibiti awọn Atinga gbe nsere osi njo tikara-tikara ṣugbọn ẹpa ko boro mọ Awọn Atinga si bẹrẹ si kọrin bayi pe:-

Onigbagbọ kekere
ṣe! ki nrọna mi lo

## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) – Bi o ba ni idalẹ kan lati lọ, bẹrẹ rẹ loni irin ajo ra yio suwọn fun ọ.

PISCES (Feb 21–Mar 20) – M ṣe ṣabosi fun ẹnikan loni, toripe o ngbero lati fi ẹjẹ sinu ki o si tu itọ funfun jade. Bẹni ki o ma ṣe dajọ abosi pẹlu. Ojulumọ rẹ kan yio ṣe ohun ribiribi fun o.

ARIES (Mar 21-Apirl 20) – Laju silẹ ki o ma wo bi nkan ti nlọ si orire yio rogba yi ọ ka, tobẹ ti nwọn ko imọ riri airowon na.

TAURUS (April 21-May 20) – Ṣe gbogbo nkan ti o nişe ni ọwọ owurọ yi nitoripe aye rẹ le ma si ni ọwọ irọlẹ Ṣọra ni pa ọrọ isọkusọ kan yio bọ lẹnu rẹ.

GEMINI (May 21-Jan)- Bi Ọlọpa ba mu ọ, wọ yio ri ọna lati salọ bẹni ki o maṣe kanra mọ ẹnikan Irawe re yi ran o lọwọ.

CANCER (Jun 22–July 23)-Maṣe fi ara silẹ fun otutu loni bẹni ki o maṣe sarẹ nsẹ amodi nla, Ṣugbọn fun igba diẹ ni.

LEO (July 24 - Aug 22) Gbogbo laalaa rẹ ko ni jẹ asan sa li ori ti i, ọjọ oni yio si dara fun ọ. omọ ọdọ rẹ kan yio gbayi, ohun ti o fẹ da silẹ yio sunwọn fun ọ. Ṣugbọn mura lati pari ija ti o mbẹ larin iwọ pelu ẹnikan.

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Ohun kan ti o mba ọ lẹru ti pora, Rere airotẹlẹ yio de wa ba ọ loni, bi ọwọ rẹ ba tẹ ẹ. maşe jẹki o lọ.

LIBR (Sept 24 - Oct 22) Maşe diba ti owọ rẹ ko le tọ, bẹni ki o maṣe ohun kan laifi si ero. Awọn ti o wa yi ọ ka le ma binu ṣugbọn iwọ ko gbọdọ binu, Iran lọwọ lo dara fun ọ lati ma ṣe.

SCORPIO (Oct 23 - Nov 22) Maşe gbẹkẹle ẹnikan Ọdẹ kan ti iwọ yio lo yio fa ire wa ba ọ şe pelẹpẹlẹ ki o si ma şe jẹjẹ, maṣe ro ohun kan nipa dukia tirẹ, sugbọn ro ti awon to ṣowon fun.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 22) Maṣe fi ọwọ gẹngẹ mu iṣẹ rẹ, Imure ko ni ran bi o ba lọ jẹki iṣẹ na bọ.

CAPRICORN (Dee. 23 - Jan. 21) Alafia yio to ọ loni tobẹ ti iwọ yio fi le dojukọ gbogbo iṣoro ti o wa niwaju rẹ, maṣe şe rikişi bẹni ki o maşe ba wọn ditẹ buruku ti ko kan ọ lọwọ lẹsẹ.


# Gbanjo o !

Eyi ni lati kede fun gbogbo awn ONIBARA wakọ jake jado agbaiye pe ao bẹrẹsi ma a ta Ọja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi işe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Cotonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tete bẹrẹ GBANJO na.

TETE WA RA TIRẸ LONI

ỌJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 28th MAR.–30th APR

Iwe Igbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6d
Iwe Ilana Ifa, Iyanrin tite Etutu şişe 21/- di 18/-
Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba Psalm Isẹgun Ajẹ 4/6d di 3/-
Iwe Ala Nla 7/6d di 5/6d
Iwe Ala ati Iwadi Nkan 2/6- di 2/-
Turari Isẹgun Ajẹ 10/6 di 8/-
Certificate of Appreticeship 7/6d di 5/-
Tailor's Measurement Book 7/6d di 5/6d
Iwe Itan Ala 2/6d di 1/-
Iwe Itumọ Ami Ara 4/6d di 3/-

AKIYESI:— Ẹnikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba TURARI IŞẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

**Shoyinka**
N2/99 Shittu Street
Ibadan



BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANŞE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yato patapata si awọn

# RICHALET

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọn mọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe n TỌNIKI Ẹẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn şe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba awọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranşẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, La kuregbe, orisirisi Inarun, Oju şuşu tabi didun. Jẹdiẹdi Akọ ba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalap Egbogi-n Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didu tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogi kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si n ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹlu.

Şa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomitan pelu

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

# Eyi ni awon ojo Oja Ile Yoruba

## OJO AJE APRIL 21 (MONDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Obun-Eko, Ojuwoye,Ikosi, Epe Atan, Agbado. Ifo, Itori, Itoku Isabo, Odeda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fedegbo, Oyedeji, Egbeda, Babalokuta' Ijaiye-Orile |
| IJEBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imopesara, Imodi, Ishan, Akesan, |
| JESHA | Epe, Iloba. Imuroko, Erinmoo Ilase, Iperindo |
| EGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

## OJO ISEGUN APRIL 22 (TUESDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE . ABEOKUTA | Mushin, Badagary Otta, Abalabi, Sodeke, Omida Ilawo |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Towobowo Temidire |
| IJEBU | Ikenne, Okun—Owa Eruwon, Omu. Mamu |
| JESHA | Osnu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| EGBADO | Igbogila Ijoun, Imasai Owode Oke-Aiyedun, Ikole |
| EKITI | |

## OJO'RU APRIL 23 (WEDNESDAY)

| ILU | ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Ikeja, Agege, Ebute-Ero Ojo Ajido Lafenwa, Obada, Oba, Kajola Ajegunle, Idogo Olodo |
| IBADAN | Lalupon, Ajegunle Owode Igbo-Ora |
| IJEBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijebu-Ijesha, Isara, Imodi Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, |
| IJESHA EGBADO | Lasilo, Idiemi Okemesi Ifaki |
| EKITI | Ijebu-Ijesha |

## OJO OJOBO APRIL 24 (THURSDY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Oyingbo Ijoko Iberekodo, Asu. Wasinmi, Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idofin, Lagun, Sagbe Ogunjana, Molete |
| IJEBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Remo |
| IJESHA | Ibodi, Ibode, Kajola, Imesi Ile |
| EGBADO | Alagba, Ilaro, Oja-Odan, Sunwa, Iboro |
| KITI | Ilogbo, Ishan |

## OJO ETI APRIL 25 (FRIDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Obun-Eko, Ojuwoye Atan Agbado, Ifo Itori, Itoku Isabo, Odeda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fedegbo, Oyedeji, Ogburo, Egbeda Babalokuta, Ijaiye Orile. |
| IJEBU | Ilishan, Isara, Imodi. |
| IJESHA EGBADO | Epe, Iloba, Imuroko, Erinmo. |
| EKITI | iyetoro, Ado-Oda. Agosi, Odo-Aiyedun. |

## OJO ABAMETA APRIL 26 (SATURDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Mushin Otta, Abalabi, Sodeko Omida Itwo |
| IBADAN | Itoko, Sojukonko Towobowo Temidire |
| IJEBU | Ikenne, Okun-Owa Eruwo Omu Mamu |
| IJESHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idoko Iloko |
| EGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owod |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikole |

## OJO AIKU APRIL 27 (SUNDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGEEGBE RE ABEOKUTA | Ikeja, Agege Lafenwa, Obada, Oba, Kajola Ajegunle, Idogo, Olodo, |
| IBADAN | Lalupon, Ajegunle, Owode Igbo-Ora |
| IJEBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijebu-Ijesha, Isara, Imope Iwara Ejiro, Odo, Ibokun |
| IJESHA | Ijebu-Ijesha kasilo-Idiemi |
| EGBADO | |
| EKITI | Okemesi, Ifaki. |

## OJO AJE APRIL 28 (MONDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Oyingbo, Ejinrin Ijoko, Berekodo, Asu, Wasinmi, Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idofin, Lagun, Sagbe, Ogunjau, Molete, |
| IJEBU | Aiyepe, Shagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Remo, Oyingbo |
| IJESHA | Ibodi, Ibode, Kajola, Imesi-Ile |
| EGBADO EKITI | Alagba, Ilaro, Oja-Odua, Sunwa, Iboro, Ilogbo Ishan. |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Owo EJO'NGBORO

ZANZIBAR

Irinwo (400) enia ni nwon tibinu jade ninu ilu nitori rogbodiyan kan ti o ti wa larin ilu na lati bi osu die sehin

MACON

Oniwasu kan, M. Simmons ni adajo Ile ejo kan ti se idajo fun pe ki o lo ewon osu meji nitoripe o npariwo nigbati awon enia nse isin lowo ninu ile re. Sosi na wa ni eti ile re.

DURBAN

Adajo Ile ejo ti o gajulo ti se idajo iku fun awon enia m e j i kan nitoripe nwon jebi esun pe, awon lo fo ile kan, nwon ba obinrin kan lopo peiu ipa, nwon pa obinrin na nigbati o npariwo, nwon sin tun ko gbogbo eru re lo.

MAIDUGURI

Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati awon ibeji kan ku ni ojo kanna ogbeni Sy-locter ti ise baba awon omo mejeji na se alaye si ikuiyanu ti awon omo re mejeji na ku,

EKO

Awon omo Olola Azikiwe meji Nwachukwu Abiodun Azikiwe, eni odun mokandinlogun ati aburo re obinrin Ngozi Azikiwe, eni odun metadinlogun ba oko oju omi kuro ni Eko lo si ilu Oyinbo lati tun lo ko eko si i.

IBINNI

Ogbeni Henry Oleari okan ninu awon ti o wa jeri fun Ijoba ninu ejo oloye Awolowo lo sare wa si Eko lodo Tafawa Balewa pe ki o gba on kale lowo awon ilu on nitoripe, lati igbati on ti jeri ninu ile ejo lodi si Awolowo ni awon ara ilu on ti nwa ona lati on.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 584 MONDAY, APRIL 20, 1964 (2D)


## NwỌn Mu Olotu Iwe Irohin 'Tribune'

IBADAN:— Idaamu nla ba gbogbo awọn oṣiṣẹ Ile iṣẹ "African Press" nibiti nwọn ti ntẹ Iwe Irohin Yoruba, Nigerian Tribune ati Service Magazine, nigbati ogunlọgọ awọn Ọlọpa wọ inu Ile iṣẹ na lọ ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe kẹrindinlogun oṣu yi nigbati nwọn ri ọrọ kan ti o jade ninu iwe Irohin na.

Alapara Ibadan, sọ fun oniwe irohin wa pe, idi gbogbo awọn enia lo di omi nigbati awọn Ọlọpa de ti nwọn si nbere Olotu ' Iwe Irohin Tribune"

O ni nigbati nwọn ri Olotu na ni nwọn ba mu on ati awọn enia diẹ pẹlu re lọ si Teṣan nwọn si bi wọn lere awọn ọrọ diẹ ki nwọn to fi wọn sile lori idaduro ati onigbọwọ.

Irohin fi ye wa wipe ohun ti o fa ni, ọrọ kan ti Olotu Iwe Irohin na, Ọgbẹni Ayọ. Ọjẹwumi onigegewura kọ sinu iwe irohin rẹ ọjọ na.

Alapara Ibadan sọ fun oniwe irohin wa pe, "Ọrọ na fa kiki, ọrọ pọ ninu iwe kọbọ" o ṣe alaye pe bi awọn Ọlọpa ti nlọ ti nwọn si mbọ nwọn ko ri on nibiti on lugọ si, ti on si nwo wọn. Bi nwọn ba ti pari ọrọ na si, ẹ o ma a gbọ o.

LATI OJU EWE KINI

lẹhin eyi ti awọn adajọ na fi pada si ori aga ijoko wọn lọ lẹhin isimi iseju medogun.

**Ki awọn adejọ to de, ni olukuluku enia ti joko si aye rẹ ti gbogbo ile si palọlọ pẹlu awọn ọlopa ti nwọn duro pẹlu ibọn pokiti pokiti lọwọ won, yika Ile ẹjọ na**

**Gbogbo awọn olujẹjọ na ni. nwọn joko pẹlu ifọkanbalẹ, ti nwọn si rẹrin si gbogbo enia, ọkan wọn balẹ, awọn ẹlomiran ninu wọn sanran, nwọn tun nyọkun, oju wọn ndan.**

Nigbati awọn adajọ na joko lori aga ijoko wọn tan, ni Ọgbẹni Ayọọla tun mba ọrọ rẹ lọ; ṣugbọn ko sọrọ ọgbọn iseju ti Adajọ Agba Ọlọla Adetokunbọ Ademọla ṣe a k i y e s i ọgbẹni Ayọọla, o si sọ fun un pe.

Adajọ:-mo se akiyesi pe, aarẹ ti de si ọ, o dabi ẹnipe o yẹ ki o simi diẹ.

Ayọọla:- Oluwa mi. aarẹ ti de simi, nko mọ wipe ẹnyin na nṣe akiyesi mi bi mo ti nṣe.

Lẹhin eyi ni Ọ g b ẹ n i Ayọọla sọrọ diẹ lori ọrọ ti Ọgbẹni Ayo Adesanya, o si ṣe alaye pe, adajọ si ara rẹ lọna, nitoripe o gba ẹri a w ọ n Ọgbẹni Henri Oleari ati Anthony Oboh gbọ o si kọ ẹri a w ọ n iyawo olujẹjọ.

Ọrọ yi ni ọgbẹni olu. Ayọọla sọ, ti asiko na fi to 'agogo kan abọ ọsan (1 : 30 p. m.) Ile ẹjọ na si mu ipade wọn ọjọ na wa si opin. Nwọn o si tun maa ba ijoko wọn lọ ni owurọ yi nigbati Ọgbẹni Olu. Ayọọla yio tun maa ba ọrọ rẹ lọ.

Ọrẹ nyin Ejongboro yio si tun maa fun nyin ni irohin Ile ẹjọ na ni owurọ ola.

Onirohin wa kan fi ye wa pe gbogbo awọn enia ti o wa ni Igbobi ati Shomolu ni nwọn nsare wọ moto wa si Eko ni ọsan ijerin nigbati awọn kan sọ fun wọn pe, "Lati Eko ni a ti mbọ yi, Adajọ ti da Oloye Awolọwọ silẹ"

Irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn ero ọja ati awọn ti nta wosiwosi ni ode n i nwọn sare palẹmọ ti nwọn si mura lati wa si Eko, nigbati awọn kan ti sure wa si Eko ti nwọn si gbọ pe ọrọ na ko ri bẹ, ni nwọn b a tete peda wale wa sọ fun awọn enia wọn pe, "Irọ ni nwọn pa fun wọn adajọ ko ti pari ẹjọ Oloye Awolọwọ.

LATI OJU EWE KEJI

Geeẹbi orin Ogunde, gbogbo ere rẹ ati orin re jẹ ẹkọ fun gbogbo enia Oloye si ni ọrọ mba wi.

**Ni** ọjọ t' Ogunde kọkọ ṣe ere yi mọ si lọ woran ere na' omi bọ l o j u mi pẹrẹpẹrẹ nigbati o de ibiti o ti kọ orin Y o r u b a RONU," sugbẹn n i n u awọn ti ojo'to ti mi ti oye ko ye to nrẹrin ni ọjọ na bi o tilẹ jẹ pe awọu ẹlomiran dori kodọ O ronu fun nkan b i iseju melo kan ti awọn fi kọ orin na

Ko s i ohun meji t i o mu mi sunkun ni ọjọ na ni pe nigbati mo ro gbogbo rẹ lọ ti m o si ranti awa ọdọ ati awọn iran t i o si mbọ wa ẹru mba mi, ominu si kọ mi pẹlẹ.

Nitori ti a ko ba tete mojuto ọnọ na nisisiyi, lẹhin ọla iya yio ma jẹ awọn ọmọ wa, Awọn I p i n l ẹ Yoku ni yio si ma mu awọn ọmọ wa sin bi ẹru, nitorina ẹ wa tete moju to ọrọ na ẹnyin agba.

Ẹnyin agbalagba, o di ọwọ nyin o, ẹronu jinlẹ ki ẹ ba wa wa ọgbọn ti ẹ o fi tun ilu wa ṣe, ẹ jẹki a gbadura, ki a si ṣe ọpọlọpọ etutu fun idapada iṣọkan, Alafia ati idẹra ilẹ wa ki agbadura ki ifẹ owo kuro ni ọkan awa Yoruba.

Ẹ jẹki a tun ilẹ wa ṣe, ẹ sanu a w ọ n ọmọde, ẹ maṣe jẹki iya jẹ a w ọ n iranti o mbọ.

Lakotan mo fi Oduduwa bẹ nyin o, Oduduwa na yio tan nyin lọwọ, ẹ dide s i ọrọ yi o. O di ọwọ nyin o.


## Never

refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



## LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.



Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Fanㅤgbore Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Barige 20/464